## ÈRÈ IGBAGBỌ́ ATI IFORITI

**Matteu 15:21-31; Marku 7:31-37**

**ẸKỌ 96 – FUN AWỌN AGBA**

**AKỌSORI: "O ṣe ohun gbogbo daradara" (Marku 7:37).**

**I Jesu ati Obinrin Ara Sirofenikia Kan**

1. Jesu kọja ni agbegbe Tire on Sidoni, Matteu 15:21
2. Obinrin Keferi kan kigbe fun aanu, Matteu 15:22, Marku 10:47
3. A kò dá a lohun awọn ọmọ-ẹyin fẹ ki a lé e kuro lẹyin wọn, Matteu 15:23; Johannu 11:6
4. Jesu wi pe a rán Oun si awọn agutan ile Israẹli ti o ti sọnu, Matteu 15:24; 9:36
5. O wolẹ fun Jesu o si bẹbẹ fun iranwọ, Matteu 15:25
6. Jesu sọ fun un pe kò tọ́ ki a fi akara ọmọ fun awọn ajá, Matteu 15:26
7. 7 Igbagbọ́ ati iforiti rẹ mú èrè wá. Matteu 15:27, 28; Jakọbu 1:3; I Peteru 1:7

**II Jesu ati Ọkunrin ti O Diti**

8. Jesu bá ọna Dekapoli wá si Okun Galili, Marku 7:31
9. Wọ́n mú ọkunrin aditi kan wá, wọn si bẹ Jesu ki o mu un lara da, Marku 7:32; Matteu 9:32; Luku 11:14
10. Jesu fi ika Rẹ si ọkunrin naa leti, O si fi ọwọ́ tọ́ ọ ni ahọ́n, Marku 7:33, 34; 9:23
11. Loju kan naa eti rẹ ṣí, okùn ahọ́n rẹ si tú, Marku 7:35; Isaiah 35:5, 6
12. Ijọ eniyan kun fun ọpẹ́ wọn si wi pe, "O ṣe ohun gbogbo daradara," Marku 7:36, 37

## ALAYE

### Obinrin Ara Sirofenikia

A ri i pe nigba ti Jesu wà ni aye, laaarin awọn Ju ni O ṣiṣẹ iranṣẹ Rẹ. O wi pe a kò rán Oun bikòṣe si agutan ile Israẹli ti o sọnu, ṣugbọn Oun kò mú eti kuro ni igbe awọn ti o wà lẹyin agbo nigba ti wọn ba n fẹ iranwọ Rẹ. Gẹgẹ bi o ti jẹ pe Oun kò "le ṣaima" gba aarin Samaria kọja ni ọjọ kan, a gbagbọ́ pe bẹẹ naa ni O gba eti okun Tire on Sidoni kọja nitori ni ebute wọnni iya kan wà ninu wahala. Eṣu n dá ọmọbinrin rẹ loro gidigidi. Dajudaju iya naa ti gbiyanju lọna gbogbo lati yọ ọmọbinrin rẹ; ṣugbọn kò bọ́ si i. Nigba ti o gbọ́ okiki Jesu ati pe O si n rekọja lọ ni agbegbe wọn, yoo ti wi lọkan ara rẹ pe, "Emi o lọ wá iranwọ Rẹ." O ni ireti pe ọmọ oun le tun sàn sibẹ. Wahala ti mu ọpọ ọkàn wá si ẹsẹ̀ Jesu. Bi a ti n feti si ẹri awọn ẹni irapada Oluwa laaarin ipade wa gbogbo, a ri i pe pupọ eniyan ni o tọ Jesu wá ti wọn n wá ọna ati bọ́ kuro ninu wahala wọn. Pupọ ninu wọn ni o ti jẹ olupọnju, ti a dè lati ọwọ́ eṣu, gẹgẹ bi ọmọbinrin yii ti rí. Wọn ri i pe Ihinrere ní agbára bakan naa lati gbala lonii gẹgẹ bi o ti ri ni ẹgbẹwa ọdun sẹyin.

### Adura Onirobinujẹ Ọkan

Ara Kenaani ni a pe obinrin yii nitori iran ibi ti o ti dide. Marku pe e ni ara Sirofenikia nitori ilu ibi ti o n gbé. Nipa pipe Jesu ni Oluwa, o gba A gẹgẹ bi Ọlọrun. O ni lati ti mọ̀ nipa itan awọn Ju nitori o pe e ni Ọmọ Dafidi. Adura rẹ kuru, ṣugbọn gbogbo ọkàn ati ẹmi rẹ ni o fi gbà á -- Ṣãnu fun mi." Eyi ni pataki adura ti olukuluku ẹlẹṣẹ n gbà. Adura onirobinujẹ ọkàn ni. Yoo dé ọdọ Jesu dandan. O le má dahun lẹsẹkẹsẹ gẹgẹ bi eyi yi, ṣugbọn Oun ki yoo ta onirobinujẹ ọkàn nù lae.

### Iforiti

Jesu kò dá a lohun ni akọkọ. A le má tete ri esi adura wa gbà lẹsẹ kan naa ṣugbọn o yẹ ki iforiti obirin yii kọ́ wa lati tubọ taku ti Ọlọrun. Awọn ọmọ-ẹyin fẹ lati le e pada. Nigba pupọ eniyan ko le mọ ero ọkàn onirobinujẹ eniyan, wọn a si fẹ lati ta a nu lai ni iranlọwọ. Eniyan a maa wo oju ṣugbọn Ọlọrun a maa wo ọkàn. Jesu wi pe, "A kò rán mi, bikọṣe si awọn agutan ile Israẹli ti o nù" (Matteu 15:24). Eyi le kó aarẹ bá ọpọ eniyan ṣugbọn nitori Jesu sọrọ si i rara, o fun ọkàn rẹ ni igboya, nitori o sun mọ Ọn, o si wolẹ fun Un o wi pe, "Oluwa, ràn mi lọwọ. Jesu wi pe, "Ko tọ́ ki a mu akara awọn ọmọ, ki a fi i fun ajá." Eniyan pupọ ninu ayé lonii ni i ba binu si iru abuku bayii, wọn i ba si pada sẹyin pẹlu ibinu gẹgẹ bi Namaani adẹtẹ. Ṣugbọn pẹlu igboya nla yii, obinrin naa wi pe, "Bẹni, Oluwa: awọn ajá a ma jẹ ninu ẹrún ti o ti ori tabili oluwa wọn bọ́ silẹ." Idahun yii mu ọ̀kan ninu awọn ọrọ iyin ti o ga ju lọ wá lati ẹnu Oluwa: "Obinrin yi, igbagbọ́ nla ni tirẹ: ki o ri fun ọ gẹgẹ bi iwọ ti nfẹ." Nigba pupọ ni Jesu bá awọn ọmọ-ẹyin wi nitori igbgbọ́ wọn kere. Wọn ti ri iṣẹ iyanu ti O ṣe lati igba de igba. Boya obintin ara Kenaani yii kò i ti ri ki a ṣe iṣẹ

iyanu kan ri, ṣugbọn ninu ọkàn rẹ̀, o gbagbọ́ pe Ọmọ Ọlọrun ni Jesu i ṣe, O si ni agbára lati ran oun lọwọ. O foriti iṣoro titi iranlọwọ fi de. Pupọ igba ni a n kuna ogo ti i ba jẹ ti wa bi o ba ṣe pe a ti mú suuru, ki a si ni ifarada diẹ!

**"Rọju duro, Rọju duro,**

**Iṣẹgun fẹrẹ de na,**

**Akoko na fẹrẹ de na;**

**Rọju duro, Rọju duro."**

Ni wakati naa ni ọmọbinrin naa sàn. Iwe Mimọ́ ni ṣẹ ti o wà ninu Isaiah pe, Oun de lati ṣe awotan awọn onirobinujẹ ọkàn, lati kede idasilẹ fun awọn igbekun (Isaiah 61:1). Nigba gbogbo ni ironupiwada ti o dapọ mọ́ igbagbọ́ tootọ maa n mu ère wá. Igbagbọ́ obinrin onirẹlẹ yii kọ́ wa ni ọ̀kan ninu awọn ẹkọ ti o ga ju lọ lori igbagbọ ati iforiti ti a sọ ninu Ọrọ Ọlọrun. Bi a ti n gbọ́ ti a si n ka Ọrọ Ọlọrun pẹlu ọkàn ṣiṣipaya, bẹẹ naa ni igbagbọ́ n dagba soke si i lọkan wa; nitori nipa igbagbọ́ ni a fi duro (2 Kọrinti 1:24). Nipa igbagbọ́ ni a n rìn (2 Kọrinti 5:7), a wà laaye nipa igbagbọ́ (Galatia 2:20). Ninu Iwe Heberu a sọ fun ni pe igbagbọ́ ni idaniloju ohun ti a n reti, ijẹri ohun ti a kò rí, ati pe lai si igbagbọ o ṣoro lati wu Ọlọrun. Ẹni kan bayii sọ pe igbagbọ́ kekere yoo mu ọ de Ọrun, ṣugbọn igbagbọ nla ni yoo fa Ọrun sinu ọkàn rẹ.

### Mimu Awọn Ọkàn Wá Sọdọ Jesu

Ọkunrin aditi ti o wà ninu ẹkọ wa yii jẹ́ alailagbara, kò si le gbọ́ ki a sọ iṣẹ iyanu ti Jesu n ṣe fun un. Ninu ipo ikaanu rẹ̀ kò mọ pe igbala wà fun oun. O kù si ọwọ́ awọn ti wọn mọ̀ lati mu un wá sọdọ Jesu. Ọpọlọpọ eniyan ni wọn n ṣaisan ti wọn kò si lagbara, ti wọn wà lori akete ninu irora ni ile wọn ati ni ile itọju alaisan. Wọn kò gbọ́ rí pe Jesu le wo eniyan sàn, tabi pe igbala wà fun wọn nipa Ẹjẹ Rẹ̀ iyebiye. Iṣẹ ti wa ni lati sọ itan naa fun wọn ati lati mú wọn wá sọdọ Jesu.

### Agbara Ifọwọtọ Kristi

Nigba ti wọn mú ọkunrin yii tọ Jesu wá, wọn bẹ Ẹ pe ki o gbé ọwọ́ Rẹ̀ le e. Wọn ti mọ agbara ti ó wà ninu ifọwọtọ Rẹ̀. A kà ninu 1 Awọn Ọba 18:46 pe, "Ọwọ́ Oluwa si mbẹ lara Elijah: o si di amure ẹ̀gbẹ rẹ̀, o si sare niwaju Ahabu titi de Jesreeli." Agbara ọwọ́ naa ti o wà lara Elijah mú ki o le sare ju bi Ahabu ti le sare lọ ninu kẹkẹ rẹ̀. Nigba ti Jesu fi ika Rẹ̀ si eti ọkunrin aditi naa ti O si fọwọ tọ́ ahọ́n rẹ̀, ti O si wi pe, "Iwọ ṣi" lẹsẹ kan naa eti rẹ̀ ṣí, okùn ahọ́n rẹ̀ si tú, o si sọrọ ketekete.

### Ohun Gbogbo Daradara

Ẹnu ya ọpọ eniyan ṣugbọn wọn wí lati inu ọkàn wọn pe, "O ṣe ohun gbogbo daradara." Nigba ti a ba bojuwo ẹyin ti a si ronu lori ohun gbogbo ti Oun ti ṣe fun wa ati ọna ti ọwọ Rẹ̀ fi gba n pa wá mọ́ ti O si n tọ́ wa, a ko ha ni wi pẹlu wọn pe, "O ṣe ohun gbogbo daradara?" Jesu kò fẹ́ okiki, O si kilọ fun awọn eniyan pe ki wọn má ṣe sọ fun ẹni kan; ṣugbọn ọkàn wọn kun fun ayọ̀ ati ọpẹ́, wọn si tubọ royin naa kaakiri, nitori ki i ṣe ohun ti wọn le bò mọ́ra. Nigba ti agbara iwosan Rẹ̀ ba kàn wá lara, tabi ti Ẹjẹ Rẹ̀ wẹ ọkàn wa mọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ, ayọ̀ a kún ọkàn wa, yoo si dùn mọ́ wa pupọ to bẹẹ ti a kò ni le fi pamọ lai sọ ni gbangba. A fẹ ki awọn ẹlomiran mọ̀. "Ihinrere" ni iroyin didun, a si n fẹ sọ fun gbogbo agbaye nipa rẹ̀.

### AWỌN IBEERE

1. Nibo ni Jesu wà lakoko ẹkọ yii?
2. Awọn eniyan wo ni a rán Jesu si?
3. Orilẹ-ède wo ni obinrin ti o tọ Jesu wa yii i ṣe?
4. Ki ni iwọ ro pe o ga ju lọ ninu iwa rẹ̀?
5. Bawo ni o ṣe gba èrè?
6. Ki ni ohun ti Jesu wí nipa rẹ̀?
7. Bawo ni Jesu ṣe mu ọkunrin aditi naa lara dá?
8. Bawo ni o ṣe mọ nipa Jesu nigba ti oun kò le gbọran?
9. Ki ni awọn eniyan sọ nipa Jesu lẹyin iṣẹ iyanu wọnyii?